# Gbígba abẹ́rẹ́ àjẹsára ọ̀fìnkìn

## Tani o yẹ ko gbàá àti kíni ìdí

Ó pẹ̀lú ìwífún fún àwọn òbí
àti àwọn obìnrin tó lóyún



Flu immunisation
Ríran ni lọ́wọ́ láti dáàbòbò àwọn ènìyàn, gbogbo ìgbà òtútù

Main winter flu leaflet 2024-2025 - Yoruba.indd 1 27/08/2024 11:46:51

## Ìwé pélébé ńsàlàyé bí o ṣe le ṣe ìrànlọ́wọ́ ààbò ara rẹ àti àwọn ọmọ rẹ tako ọ̀fìnkìn ní ìgbà òtútù yìí tó ńbọ̀, àti ìdí tí ó fi ṣe pàtàkì gidigidi pé kí àwọn ènìyàn tó wà ní ewu ọ̀fìnkìn gíga gba abẹ́rẹ́ àjẹsára ọ̀fẹ́ lọ́dọọdún.



### Kíni ọ̀fìnkìn? Ṣé kìíṣe òtútù líle lásán ni?

Ọfinkin nṣẹlẹ lọdọọdun, paapaa julọ ni asiko otutu, idi eyiti o fi jẹ wipe a npe ni igba ọfinkin nigba miiran. Aisan iranmọ to le gidigidi ni pẹlu awọn aami aarun to ma njẹyọ kiakia. Awọn otutu ko le pupọ o si ma nbẹrẹ ni sisẹntẹle pẹlu imu didi tabi riro ati ọgbẹ ọfun. Ọwọja ọfinkin buburu le buru ju otutu lile lọ.

Ọfinkin le fa iba, àádùn lile, àwọn isan ati orikerike ara riro, imu didi, ikọ gbigbẹ ati ọgbẹ ọna ọfun. Awọn eniyan di ara wọn da ma nsaba gbadun laarin ọjọ meji si meje, sugbọn fun awọn kan aarun naa le yọri si lilọ si ile-iwosan, ailagbara patapata tabi iku paapaa.



**Awọn abẹrẹ ajẹsara ọfinkin ṣe iranlọwọ aabo tako iru kokoro aarun ailefojuri ọfinkin pataki ti nja kiri**

## Kini o nfa ọfinkin?

Ọfinkin ti awọn kokoro aarun ailefojuri influenza fa eyiti o nranmọ ọna ọfun ati ẹdọ foro. Ati nitoripe awọn kokoro aarun ailefojuri lo nfa ti kii si ṣe kokoro aarun afojuri, oogun aporo aarun ko le tọju rẹ. Ẹwẹ, bí àwọn idiju ba wa lati ni ọfinkin, o le nilo oogun aporo.

## Bawo ni o ṣe le ni ọfinkin?

Nigbati ẹni toni ọfinkin ba wukọ tabi sín, àwọn eniyan yooku yoo fa awọn itọ fifọn wọnyi simu tabi ki wọn ko nipa fifi ọwọ kan awọn ibi ti awọn itọ wọnyi bọ si. O le dena itanka awọn kokoro arun ailefojuri nipa fifi ọwọ bo ẹnu ati imu rẹ nigbati o ba wukọ tabi sín (pẹlu ẹya ara kan, tabi sinu kọrọ igunpa rẹ), o si le fọ ọwọ rẹ loorekoore tabi lo oje ifọwọ lati din ewu kiko kokoro aarun ailefojuri.

Sugbọn ọna to dara julọ lati yago fun kiko ati itan ọfinkin ka ni nipa gbigba abẹrẹ ajẹsara saaju ki igba ọfinkin to bẹrẹ.

## Bawo ni a ṣe le ni aabo tako ọfinkin?

A ko le sọtẹlẹ nipa ọfinkin. Gbigba abẹrẹ ajẹsara npese aabo to dara julọ. Orisirisi iru kokoro aarun ailefojuri lo wa. Iru eyi to seeṣe ko fa aisan ni a ma nri ni igba otutu lile. A ti wa ṣe awọn abẹrẹ ajẹsara lati tẹ wọn mọlẹ bi o ti yẹ. Koda bi abẹrẹ ajẹsara ko ba tẹ iru kokoro yi mọlẹ daradara o ma nsaba pese awọn aabo kọọkan tako o.

A ma nfunni ni abẹrẹ ajẹsara naa ni igba irẹdanu saaju ki ọfinkin to bẹẹrẹ si tan kaakiri.

## Iru akoba wo ni ọfinkin le ṣe?

Awọn eniyan ma nro nigba miiran wipe ọfinkin ni otutu buruku, sugbọn ninu ọfinkin le buru lẹẹkọkan ju otutu lọ o si le nilo lati wa lori ibusun rẹ fun awọn ọjọ diẹ. Ni ipo to buru julọ, ọfinkin le yọri si didaduro si ile iwosan, tabi iku paapaa.

Awọn eniyan kan f'aragba atunbọtan ọfinkin. Fun wọn, o le mu ki ewu nini aisan lile ga sii bii otutu aya, tabi ki o mu ki awọn ipo wọn lọwọlọwọ buru sii.



Main winter flu leaflet 2024-2025 - Yoruba.indd 3 27/08/2024 11:46:56

## Nję mo wa ni ewu giga lati ọwọ awọn atubọtan ọfinkin?

Ọfinkin le mu ẹnikẹni sugbọn bi o ba ni ipo aisan ọlọjọ pipẹ, awọn atubọtan ọfinkin le mu ki o buru sii bi o ko ba ṣe amojuto ipo naa daradara ki o si gbadun daradara. O gbọdọ gba abẹrẹ ajẹsara ọfẹ bi o ba:

- lóyún

tabi o ba wa ni ipo ọlọjọ pipẹ bii:

- ìsoro ọkàn
- aroye aya kan tabi awọn isoro mimi lile, pẹlu ẹdọ foro wuwu, afẹfẹ inu ẹdọ foro tabi awọn eniyan to ni ikọ ife (ninilo ohun ifasimu kan tabi awọn oogun)
- ààrùn kídìnrín
- ajẹsara to lọlẹ latari aarun tabi itọju (bii oogun amarale tabi itọju aarun jẹjẹrẹ)
- ààrùn ẹ̀dọ̀
- rọlapa rọlẹsẹ tabi atako ẹjẹ gbigbẹ (TIA)
- ìtọ̀ súgà
- awọn ipo ọpọlọ kọọkan, fun apẹẹrẹ ọpọlọpọ koko inu ara (MS), tabi aarun ọpọlọ
- ìkùnà Ìkẹ́kọ̀ọ́
- Isoro pẹlu ọlọ rẹ, fun apẹẹrẹ, aisan arunmọleegun, tabi o ti yọ ọlọ rẹ kuro
- tabi o ti sanra ju (BMI 49 si oke)

Akojọ awọn ipo yii kò ni itumọ. O jẹ isoro idajọ ìṣègùn. GP rẹ le ṣe ayẹwo rẹ lati ṣe agbeyẹwo iru ewu ọfinkin to nfa ailera buruku, ati paapaa ewu ailera lile rẹ lati ọwọ ọfinkin funra rẹ.

**Ṣe abẹwo si nhs.uk/flujab**



Main winter flu leaflet 2024-2025 - Yoruba.indd 4 27/08/2024 11:46:56

## Tani o yẹ ka gbero gbigba abẹrẹ ajẹsara ọfinkin?

Gbogbo awọn to ni eyikeyi ipo ta to si oju-ewe kẹrin tabi awọn ti:

- wọn dagba to ọjọ-ori 65 tabi ju bẹẹlọ
- ngbe ninu ibugbe kan tabi ile nọọsi
- wọn jẹ olutọju pataki fun arugbo tabi alailagbara eniyan
- gbigbe pẹlu ẹnikan toti din ajẹsara rẹ ku latari aarun ati itọju
- osiṣẹ ilera tabi osiṣẹ itọju awujọ
- loyun (wo ipin to kan)
- awọn ọmọ ọjọ-ori pato kan (wo oju-ewe keje)



# Eto gbigba abẹrẹ ajẹsara ọfinkin fun **awọn obinrin oloyun**

## Mo loyun Ǹjẹ́ mo nílò òmíràn ní ọdún yìí?

Bẹẹni. Oyun nṣe ayidapa bi ara ṣe nṣe awọn aranmọ bii ọfinkin. Aranmọ ọfinkin le fa ilọsoke bi awọn obinrin oloyun ati awọn ọmọ won ṣe n nilo itọju to le koko. Gbogbo awọn obinrin oloyun gbọdọ gba abẹrẹ ajẹsara ọfinkin lati daabobo ara wọn ati awọn ọmọ wọn. O le gba abẹrẹ ajẹsara ọfinkin ni eyikeyi ipele oyun, lati isẹnu siwaju síí.

Awọn obinrin oloyun jẹ anfaani lati abẹrẹ ajẹsara ofinkin nitoripe o le ṣe:

- din ewu idiju lile ku bii otutu aya, paapaa julọ ni awọn ipele oyun to gbẹyin
- din ewu iya tabi ọmọ to nilo itọju to le koko
- din ewu bibi oku ọmọ tabi ni aigbo
- ṣe iranlọwọ lati daabobo awọn ọmọ wọn ti yoo tẹsiwaju lati ni awọn ajẹsara kọọkan si ọfinkin lakoko awọn osu akọkọ aye wọn
- din anfaani ki iya ma ko aarun ran ọmọ rẹ tuntun

## Mo loyun mo si ro pe mo le ni ọfinkin. Kini ki nṣe?



Bi o ba ni awọn aamin aarun o gbọdọ ba dokita rẹ sọrọ kiakia, nitoripe bi o ba ni ọfinkin oogun kan ti o le ṣe iranlọwọ (tabi din ewuawọn ididju), sugbọn o nilo lati gba ni kiakia lẹyin ti awọn aamin aarun ba jẹyọ.

**O le gba abẹrẹ ọfinkin lọfẹ lati ọdọ GP rẹ, tabi o le wa larọwọto lati ọdọ elegbogi oyinbo tabi agbẹbi rẹ.**



Main winter flu leaflet 2024-2025 - Yoruba.indd 6 27/08/2024 11:47:03

## Awọn ọmọ mi nkọ? Ṣe wọn nilo abẹrẹ ajẹsara?

Bi o ba ni ọmọ to ju osu mẹfa lọ lọjọ ori ti o ni ọkan ninu awọn ipo ti wọn to kalẹ lori oju-ewe kẹrin, wọn gbọdọ gba abẹrẹ ajẹsara. O seeṣe ki eyikeyi ọmọ pẹlu awọn ipo wọnyi ṣe aisan lile bi wọn ba ni ọfinkin, o si le mu ki ipọ wọn lọwọlọwọ buru sii. Ba GP rẹ sọrọ nipa ọmọ rẹ nipa gbigba abẹrẹ ajẹsara saaju ibẹẹrẹ igba ọfinkin.

Awọn abẹẹrẹ ajẹsara ọfinkin kii siṣẹ daradara ninu awọn ọmọ ti ọjọ-ori wọn ko to osu mẹfa nitorinaa a ko damọran rẹ. Idi niyi to fi ṣe pataki pe ki awọn obinrin oloyun gba abẹẹrẹ ajẹsara - wọn yoo sọwọ awọn ajẹsara si awọn ọmọ wọn ti yoo daabobo wọn lakoko ibẹrẹ osu ọjọ aye wọn.

Awọn ẹgbẹ ọmọ miiran ni a tun fun ni abẹrẹ ajẹsara ọfinkin. Eyi ni lati ṣe iranlọwọ aabo tako aarun naa ati lati ba wọn din itanka rẹ ku lori awọn ọmọ yooku, eyiti o pẹlu awọn arakunrin tabi arabinrin wọn, ati, awọn obi ati obi agba wọn. Eyi yoo ran ọ lọwọ lati yago fun idi lati gba akoko isinmi lẹnu iṣẹ nitori ọfinkin tabi lati tọju awọn ọmọ rẹ pẹlu ọfinkin.

Awọn ọmọ ti a fun ni abẹrẹ ajẹsara ni ọdun yii, ni:

- gbogbo àwọn ọmọ ọdún 2 àti 3 ní ọjọ́ 31 Osù Kejọ sáájú kí gbígba abẹ́rẹ̀ àjẹsára tó bẹ̀rẹ̀ ní ìgbà ìrẹ̀dànù
- gbogbo àwọn ọmọ tí wọ́n wà ní ọjọ́-orí ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ́rẹ̀
- àwọn ọmọ tí wọ́n wà ní ọjọ́-orí ilé-ẹ̀kọ́ girama kọ̀ọkan (Ọdun meje si ikọkanla)

Awọn ọmọ ọdun meji ati mẹta yoo gba abẹẹrẹ ajẹsara ni iṣe gbogbogbo, paapaa julọ nipaṣẹ nọọsi. A ó fún àwọn ọmọ tí wọ́n wà ní ọjọ́-orí ilé-ẹ̀kọ́ ní abẹẹrẹ ajẹsara ní ilé-ẹ̀kọ́, pẹ̀lu àwọn ànfàání síwájú síi láti gba abẹẹrẹ ajẹsara, ní àwọn ilé ìṣègùn àwùjọ NHS, fún ẹnikẹ́ni tó bá pàdánù sáà náà ní ile-ẹ́kọ́. Fun ọpọ awọn ọmọ, wọn yoo gba abẹrẹ ajẹsara gẹgẹbi nkan finfin sinu iho imu kọọkan. Eyi ni igbesẹ to yara ti kosi dunni.

**Fun iwifun siwaju si lori awọn ọmọ ati gbigba abẹrẹ ajẹsara ọfinkin wo oju-ewe ayelujara iwifun NHS ni nhs.uk/child-flu.**



Main winter flu leaflet 2024-2025 - Yoruba.indd 7 27/08/2024 11:47:03

## Mo ti gba abẹ́rẹ́ àjẹsára ọ̀fìnkìn ní ọdún tó kojá. Ǹjẹ́ mo nílò òmíràn ní ọdún yìí?

Bẹẹni; kokoro aarun ọfinkin le yatọ ni igba okun kan si omiran. A ma nmu abẹrẹ ajẹsara de oju aamin fun igba otutu kọọkan lati ni aabo tako iru awọn ọfinkin to le ma fo kaakiri. Fun idi eyi, a daba imọran pe koda bi o ba gba abẹrẹ ajẹsara ni ọdun to kọja, o yẹ ki o gba abẹrẹ ajẹsara ni ọdun yii.

Bakannaa, aabo lọwọ abẹrẹ ajẹsara ọfinkin ma nlọlẹ pẹlu akoko koda bi arisirisi iru aarun ba jẹ bakannaa o gbọdọ tun abẹrẹ ọfinkin gba ni asiko ọfinkin kọọkan.

## Mo ro wipe mo ti ni ọfinkin tẹlẹ, ṣe mo nilo abẹrẹ ajẹsara?

Bẹẹni; abẹẹrẹ ajẹsara naa yoo tun ṣe iranlọwọ aabo fun ọ. Awọn kokoro aabo yooku le fun ọ ni awọn aami arun to jọmọ ọfinkin, tabi o le ti ni ọfinkin sugbọn o ju orisirisi kokoro aarun ọfinkin kan lọ, o yẹ ko gba abẹrẹ ajẹsara koda bi o ba ro wipe o ti ni ọfinkin.

## Iru orisirisi abẹrẹ ajẹsara wo loyẹ kin ni?

Orisirisi abẹrẹ ajẹsara ọfinkin lo wa. A o fun ọ ni eyiti o ba ọ lara mu julọ. Ọpọlọpọ awọn ọmọ la fun ni abẹrẹ ajẹsara naa gẹgẹbi nkan finfin simu (wo ojú-ewé 10 pẹ̀lú), awọn agba si ngba ajẹsara alabẹrẹ. Kosi ọkankan ninu awọn abẹẹrẹ ajẹsara to le fun ọ ni ọfinkin.

Bi ọmọ rẹ ba wa laarin osu mẹfa ati ọdun meji ti o si wa ninu ẹgbẹ ewu ọfinkin giga, wọn yoo gba ajẹsara ọfinkin alabẹrẹ gẹgẹbi nkan finfin simu ko bofinmu fun awọn ọmọde labẹ ọjọ-ori ọdun meji. Awọn ọmọ miiran ti ju ọdun meji lọ ti wọn wa ninu ẹgbẹ ewu giga yoo nilo lati gba ajẹsara alabẹrẹ bi ajẹsara oni finfin simu koba ba wọn lara mu.

## Njẹ awọn ọmọ mi le gba ajẹsara ọfinkin nigba kanna bii awọn abẹrẹ ajẹsara yooku?

Bẹẹni. Wọn le gba abẹrẹ ajẹsara ọfinkin lẹẹkanaa gẹgẹbi gbogbo eto abẹrẹ ajẹsara. Eto igbabẹrẹ le tẹsiwaju bi ọmọ rẹ ba ni ailera kekere bii otutu sugbọn o le ni idiwọ bi ọmọ rẹ ba nṣe aisan to le fa iba.



Main winter flu leaflet 2024-2025 - Yoruba.indd 8 27/08/2024 11:47:04

## Nję ęnikan wa ti ko yę ko gba abęrę ajęsara?

O fę ję pe gbogbo eniyan lo le gba abęrę ajęsara, sugbọn o ko gbọdọ gba abęrę ajęsara bi o ba ni aibaramu lile si abęrę ajęsara naa, tabi eyikeyi eronja rę. Bi o ba ni aibaramu si ęyin tabi ni ipo kan to ma fa àárę̀ fun eto ajęsara rę, o le ma ni pato iru abęrę ajęsara naa - şe ayęwo lọdọ GP rę. Bi o ba ni iba, o le da gbigba abęrę ajęsara duro titi o fi gbadun.

## Nipa ti Ohun finfin simu nkọ? Nję awọn ọmọ kankan wa ti ko le gbaa?

Awọn ọmọ le ma le gba abęrę ajęsara onimu bi wọn ba:

- nhan-run lọwọlọwọ tabi ti n han-run fun wakati 72 sęyin, eyiti o pęlu awọn ti o nilo alekun ohun ifasimu ikọ ife. Wọn gbọdọ gba ajęsara ọfinkin alabęrę to yę lati yago fun adaduro aabo
- ti nílò ìtọ́jú gíga látàrí
  – sí ikọ́ ife tàbí
  – àìbáramu anaphylaxis ti ęyin
  Àwọn ọmọ nínú ęgbę́ méjèèjì yìí ni a ti dáàbá láti gba ìmọ̀ràn àwọn akọ́şę́mọşę́ wọn tí a sì le gbà wọ́n ní ìmọ̀ràn láti gba abę́rę́ àjęsára onímú ní ilé-ìwòsàn
- ni ipo kan, tabi wa lori itọju, to ma n din eto ajęsara ku tabi ni ęnikan ninu ile to nilo iyęrasapakan nitoripe wọn ni ajęsara to lọolę gidigidi (bii ipaarọ mudun-mudun eegun)
- ni aibaramu si awọn eronja abęrę ajęsara miiran[1]
- bá ti ní ipò tó nílò ìtọ́jú salicylate

Bakanna, àwọn ọmọ tí wọ́n ti gba abę́rę́ àjęsára fínfín sí imú gbọ́dọ̀ yàgò fún ìfarakanra pę̀lú àwọn ènìyàn tóní işę́-ara tí kò l'ágbára (fún àpęrę àwọn tó sęşę şe ìpàárọ̀ mùdúnmúdùn eegun) fún bíi ọ̀sę̀ méjì tó tę̀lé gbígba abę́rę́ àjęsára nitoripe aaye giga wa pe ajęsara kokoro aarun naa le bọ si wọn lara. Bi ęni yii ba ję ara ile ki ọmọ naa gba ajęsara alabęrę (wo isalę).

[1] Wo oju-ewe ayelujara ni www.medicines.org.uk/emc/product/15790/smpc fun akojọ awọn eronja abęrę ajęsara



Main winter flu leaflet 2024-2025 - Yoruba.indd 9 27/08/2024 11:47:04

## Ǹjẹ́ abẹ́rẹ́ àjẹsára imú ní gẹlatini tí a gbà nínú àwọn ẹlẹ́dẹ̀ (porcine gelatine)?

Bẹẹni. Abẹ́rẹ́ àjẹsára imú ní gẹlatini to péye (porcine gelatine), èyítí a ti lò ní fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ òògùn pàtàkì. Gẹlatini nṣe iranlọwọ lati muki awọn abẹrẹ ajẹsara kokoko ailefojuri ti ko lagbara durosinsin nitorinaa abẹrẹ ajẹsara naa le sisẹ daradara.

Abẹrẹ ajẹsara onimu rọrun lati funni kosi nira. Ọmọ kọọkan to ba ni ajẹsara finfin simu gba aabo to dara julọ tako ọfinkin. A tun kaa si wipe o dara julọ lati din itanka ọfinkin ku. Ni ọna yẹn awọn ọmọ dabobo ara wọn ati awọn yooku to le wa ni ailagbara si ọfinkin. Fún àwọn tí ó le má gba ìlò porcine gẹlatini nínú àwọn ọjà ìlera, abẹ́rẹ́ àjẹsára oní gúngún mìíràn wà lárọ̀ọ́wọ́tó.

## Njẹ maa ni awọn idiju kankan?

Awọn idiju abẹrẹ ajẹsara onimu le wọpọ eyito o pẹlu imu riro tabi didi, ori fifọ, ara rirẹ ati aile jẹun. Awọn to gba abẹrẹ ajẹsara oni gungun le ni apa ni oju abẹrẹ naa, iba fẹẹrẹfẹ ati iṣan riro fun ọjọ kan tabi meji lẹyin eto gbigba abẹrẹ ajẹsara. Awọn idiju lile pẹlu abẹrẹ ajẹsara mejeeji ko wọpọ.

## Se abẹrẹ ajẹsara ọfinkin le daabobo mi patapata?

Imunadoko eto abẹrẹ ajẹsara yoo yatọtọ lati ọdun kan de ọdun kan, eyi to dale ibamu laarin iru ọfinkin to nja kiri ti o si wa ninu awọn abẹrẹ ajẹsara. Nitoripe awọn kokoro aarun ailefojuri lati ọdun si ọdun ewu wa wipe abẹrẹ ajẹsara naa ko papọ mọ kokoro aifojuri to nja kiri. Koda bi abẹrẹ ajẹsara naa ko ba baamu daradara, o le pese aabo kọọkan. Aibaramu gboogi kii saba ṣẹle.



Main winter flu leaflet 2024-2025 - Yoruba.indd 10 27/08/2024 11:47:04

## Bawo ni ma ṣe ni aabo pẹ si?

Abẹrẹ ajẹsara naa gbọdọ pese aabo jakejado asiko ọfinkin yii.

## Kini nkan ti o yẹ ki o ṣe nisinsinyi?

Bi o ba jẹ ara isọri ti a darukọ ninu iwe pelebe yii, o ṣe pataki ki o gba abẹrẹ ajẹsara ọfinkin.

Ba GP tabi nọọsi rẹ sọrọ, tabi elegbogi oyinbo agbegbe rẹ dipo, lati forukọsilẹ fun gbigba abẹrẹ ajẹsara. Fun awọn obinrin oloyun, abẹrẹ ajẹsara le wa larọwọto nipaṣẹ awọn iṣẹ igbẹbi. Abẹrẹ ajẹsara jẹ ọfẹ.

Awọn ajọ to fẹ lati daabobo awọn osiṣẹ wọn tako ọfinkin (ayafi ti wọn ba ní ipo ilera tí a tò sí oju-ewe 4) yoo nilo lati ṣe eto fifun awọn aniyan ni abẹrẹ ajẹsara nipaṣẹ awọn ẹka ilera iṣẹ ọn. Awọn abẹrẹ ajesara wọnyii ko wa larọwọto lori NHS olugbanisiṣẹ rẹ ni yoo si san owo rẹ.

Bi o ba jẹ osiṣẹ ilera tabi osiṣẹ itọju awujọ, wadii awọn eto ti o ti wa nibi iṣẹ rẹ fun pipese abẹrẹ ajẹsara ọfinkin. O ṣe pataki pe o wa ni ipamọ. Awọn osiṣẹ itọju awujọ ti wọn ko le gba abẹrẹ ajẹsara latari eti ilera iṣẹ le gba abẹrẹ ajẹsara naa nipasẹ NHS lati ọdọ GP tabi olegbooji oyinbo wọn.





Main winter flu leaflet 2024-2025 - Yoruba.indd 11 27/08/2024 11:47:07

# **Akopọ** awọn ti wọn **daba imọran** fun lati n **abẹrẹ ajẹsara ọfinkin**

- gbogbo awọn to dagba to ọjọ-ori 65 tabi ju bẹẹlọ
- gbogbo awọn ti ko tii to ọjọ-ori 65 ti wọn wa ni ipo iṣegun ti kojọ lori oju-ewe kẹrin, pẹlu awọn ọmọ ati awọn ọmọ ọwọ ti wọn ju osu mẹfa lọ
- gbogbo awọn obinrin oloyun, ni eyikeyi ipele oyun
- gbogbo awọn ọmọ ọdun meji si mẹta (bi wọn ba jẹ ọmọ ọdun meji tabi mẹta lọjọ 31, osu kẹjọ saaju ki gbigba abẹre ajẹsara to bẹẹrẹ ni igba irẹdanu)
- gbogbo awọn ọmọ ni ile-ẹkọ alakọbẹrẹ
- àwọn ọmọ tí wọ́n wà ní ọjọ́-orí ilẹ́-ẹ̀kọ́ girama kọ̀ọ̀kan
- gbogbo ẹniti ngbe ninu ibugbe kan tabi ile nọọsi
- gbogbo ẹniti o ngba owo olutọju, tabi jẹ olutọju pataki fun arugbo tabi alailera eniyan
- gbogbo osiṣe ilera tabi osiṣẹ itọju awujọ

Fun imọran ati iwifun nipa gbigba abẹrẹ ajẹsara ọfinkin, ba GP, nọọsi, elegbogi tabi ikọ abẹrẹ ajẹsara ile-ẹkọ rẹ sọrọ.

O dara julọ lati gba abẹrẹ ajẹsara ọfinkin rẹ ni igba irẹdanu tabi ibẹẹrẹ igba otutu saaju ki nini ọfinkin to lọ soke. Ranti wipe o nilo rẹ lọdọọdun, nitorinaa maṣe lero pe o wa l’aabo nitoripe o gba ọkan l’ọdun to kọja.

**Lati mọ boya o yege nhs.uk/flujab.**



UK Health Security Agency

© Crown copyright 2024. 1p 750k AUG 2024 (APS). Product code FLUMW24YO Yoruba. UK Health Security Agency Gateway number: 2024411. This leaflet is also available in braille, large print, as a BSL video and translated into 32 community languages. Please visit www.healthpublications.gov.uk or call 0300 123 1002